# IJỌ, IYAWO KRISTI

**Efesu 5:1-33**

**ẸKỌ 403 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Awa li ẹ̀ya-ara rẹ̀, ati ti ẹran-ara rẹ̀, ati ti egungun rẹ̀" (Efesu 5:30).**

**I Ṣiṣe pataki Igbesi-ayé Iwa Mimọ́**

1 A gbà wá niyanju lati maa rin ninu ifẹ, Efesu 5:1, 2; 4:1-4

2 A kilọ̀ fun wa nipa iwa ẹṣẹ, Efesu 5:3-7

3 Onigbagbọ́ maa n rin ninu imọlẹ, Efesu 5:8-13; 1 Johannu 1:7

4 Ifẹ Oluwa ni lati ra igba pada, lati maa yin ati lati maa sin Ọlọrun, Efesu 5:14-21

**II Ijọ, Ara Kristi**

1 Gẹgẹ bi iyawo ti jẹ́ si ọkọ rẹ̀, bẹẹ ni Ijọ jẹ́ si Kristi, Efesu 5:22-24

2 Ọkọ jẹ́ apẹẹrẹ Kristi ati ifẹ Rẹ̀ fun Ijọ, Efesu 5:25

3 Kristi fi Ara Rẹ̀ fun Ijọ ki Oun le mu un wá sọdọ ara Rẹ̀ gẹgẹ bi Iyawo, Efesu 5:26, 27

4 Nipa ifẹ Kristi si Ijọ Rẹ̀ a kọ́ awọn ọkunrin ni ẹkọ lati fẹran awọn aya wọn, Efesu 5:28, 29

**III Ẹwa ati Iyanu Iyawo Kristi**

1 A so Iyawo Kristi pọ̀ ṣe ọ̀kan pẹlu Kristi ninu ara awamaridi, airi ṣugbọn ti o daju, o n ṣe ifẹ Rẹ̀ pẹlu, o si n fi oore-ọfẹ Onigbagbọ tootọ hàn ninu ohun gbogbo, Efesu 5:30; Owe 31:10-31

2 Gẹgẹ bi obinrin ti i maa kọ ohun gbogbo silẹ nitori ti ọkọ rẹ̀, bẹẹ naa ni Iyawo Kristi fi ohun gbogbo silẹ ki o le ni isopọ pẹlu Kristi, Efesu 5:31, 32

3 Awọn ohun ti o de tọkọ-taya ninu ayé yii jinlẹ wọn si jẹ́ iyanu, Efesu 5:33

## ALAYE

### Igbesi-Aye Mimọ

Ijọ tootọ, Ijọ Akọbi jẹ́ ara iyanu. Ijọ gẹgẹ bi a ti mọ ọ si ni oriṣiriṣi ipa ti o pin si ninu àye yii, ifarajọ diẹ ni o ni si Ijọ ti a n kọ́ ẹkọ nipa rẹ̀ ninu Majẹmu Titun. Kristi ni Ori Ijọ, eyi si ni pe Ijọ naa wà labẹ akoso Rẹ̀ ninu gbogbo ẹkọ, ètò [ipinnu ohun ti a o ṣe] ati igbekalẹ rẹ̀. O hàn gbangba fun gbogbo eniyan lati ri i pe ki i ṣe gbogbo ọmọ ijọ ninu aye yii ni o wà labẹ akoso Kristi ninu ohun gbogbo ti wọn n sọ, ti wọǹ n rò, tabi ti wọn n ṣe. Eyi mu wa wá si opin ọrọ naa pe lati jẹ́ ọmọ Ijọ ti Jesu Kristi ju pe ki eniyan kan dara pọ mọ́ ẹgbẹ kan ninu ayé. Awọn ẹgbẹ́ ti ayé ni ipa ti wọn, ṣugbọn lati jẹ́ ọmọ Ijọ Akọbi ni ohun ti o ṣe pataki jù lọ.

A kilọ fun wa ninu ẹkọ yii lati gbé igbesi-ayé iwa mimọ́. Nigba ti Onigbagbọ bá fẹran Ọlọrun, ti o si kà ti o si n gbọran si Ọrọ Ọlọrun ti a si ti ra a pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ nipasẹ Ẹjẹ ti kò ni ẹ̀ṣẹ, ani Jesu Kristi Oluwa, yoo di ara fun un lati gbọran si gbogbo ẹkọ ti o kà ninu Bibeli. Gbogbo iṣileti si iwa-bi-Ọlọrun ni yoo fẹ́ ti yoo si fara mọ́; ati olukuluku ikilọ nipa ewu ti oun le bá pade ni yoo fetisi, nitori oun mọ pe nipa titẹle Ọrọ Ọlọrun oun n fi ifẹ ti oun ni ninu ọkan hàn fun Ọkọ Iyawo ọkan oun. Oun ko sin Ọlọrun fun erè, tabi nitori ibẹru ẹsan aisin In; ṣugbọn isin rẹ̀ jẹ́ abayọrisi ifẹ rẹ̀ si Jesu Ẹni ti o ti ṣe ohun ti o tobi fun un.

### Ikilọ

Ewu kan rọ̀ dẹ̀dẹ̀ ni akoko ti Paulu kọ Episteli yii si awọn ara Efesu; eyi ni pe awọn miiran ninu wọn le maa rin ni ọna ẹ̀ṣẹ ati ọna aimọ́ ti alaiṣootọ eniyan, ki wọn si maa tan ara wọn jẹ pe awọn tun ni ipin lọnakọna ninu Ijọba Kristi. O ká ero eke yii kuro nipa sisọ fun wọn bayii pe: "Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni fi ọ̀rọ asan tàn nyin jẹ: nitori nipasẹ nkan wọnyi ibinu Ọlọrun mbọ̀ wá sori awọn ọmọ alaigbọran." Iru ewu bẹẹ dojukọ awa paapaa sibẹ. Bi o tilẹ jẹ pe a ni ọpọlọpọ ikilọ lati inu Iwe Mimọ́, awọn miiran wà

ninu ẹ̀ṣẹ, wọn si tun n pe ara wọn ni Onigbagbọ. Ẹkọ yii ka pupọ ninu awọn ẹ̀ṣẹ naa o si sọ oju-abẹ nikó pe awọn ti o ba n ṣe iru nnkan wọnni kò ni ipin ninu Ijọba Kristi ati ti Ọlọrun.

Onigbagbọ ti kọja labẹ ẹ̀rujẹjẹ okunkun yii. Nisisiyii o n rin ninu imọlẹ ologo ti Ihinrere. Awọn nnkan wọnni ti wọn ti n bori rẹ̀, ni oun wa n bori nisisiyii. Imọlẹ Ọrọ Ọlọrun si wa n fi nnkan hàn án nisisiyii ni ọna titun, oun si korira ohunkohun ti i ṣe ibi. O gbadun ibarẹ ati ibalo Ọlọrun ati ti awọn eniyan Ọlọrun. Oun kò fẹ ibarẹ ati ibadọrẹ ayé mọ́, nitori oun mọ pe awọn nnkan wọnyii yoo fa oun pada kuro ninu ifẹ rẹ̀ si Oluwa ati Ọga rẹ̀.

**Iyasọtọ**

Awọn nnkan ti ọkàn eniyan nipa ti ara n fẹ́ maa n ti eniyan mimọ Ọlọrun loju nitori pe wọn lodi si igbesi ayé nipa ti ẹmi. Otitọ ibẹ ni pe ifẹ ọkàn Onigbagbọ si Ọlọrun ni o maa n ya a nipa kuro lọdọ awọn ti n rin ninu okunkun; igbesi-aye rẹ̀ ati ẹri rẹ̀ jẹ idalẹbi fun wọn. Ọkunrin tabi obinrin ọmọdekunrin tabi ọmọdebinrin, ti o ti yàn lati mura silẹ de ipadabọ Oluwa Jesu Kristi maa n kún fun iṣẹ Oluwa. Nnkan wọnni ti awọn miiran le ṣe ti o si dabi ẹni pe o ṣe danindanin fun wọn ni oun maa n wò bi iwa wère nitori o n fojusọna ki Oluwa rẹ̀ wa mú oun lọ lai pẹ. Awọn ẹlomiran si wi pe ohun gbogbo n lọ bakan naa “lati igbati awọn baba ti sùn” (2 Peteru 3:4). Ṣugbọn Iyawo Kristi n ṣe afẹri o si n gbadura pe ki wakati naa dé nigba ti ọkọ Iyawo yoo fara hàn lati mú Iyawo Rẹ̀ jade kuro ninu ayé yii.

**Imurasilẹ**

Bi a o ba mura silẹ de pipadabọ Jesu ki a si jẹ ọ̀kan ninu Iyawo Kristi, a gbọdọ mọ̀ ju pe Oun yoo tun pada wá si ayé lọ. A gbọdọ mura silẹ fun ipadabọ Rẹ̀ ki a si wà ni ipo imurasilẹ. A o pa wa lara dà nipa igbagbọ́, ṣugbọn a ki yoo ni irú igbagbọ bẹẹ ayafi bi Ọrọ Ọlọrun ba wẹ igbesi-ayé wa mọ́. Lai si iwẹnumọ ni ti a n ni nipa Ẹjẹ Jesu ati Ọrọ naa, ati lai si ireti ipadabọ Rẹ̀ lai pẹ ninu ọkàn wa, a ki yoo ni igbagbọ ti a o fi pa wa lara da – lati fò lọ si ofurufu nigba ti Jesu ba de.

A fi ẹkọ yii yé ni yekeyeke ninu Owe awọn Wundia Mẹwaa ninu Ori Kẹẹdọgbọn Ihinrere ti [Matteu 25:1-13]. Marun-un ninu awọn wundia naa ṣe ọlọgbọn, marun-un si ṣe alaigbọn. Iyatọ ti o wà laaarin wọn ni pe awọn ọlọgbọn ní ororo ninu kolobo wọn pẹlu atupa; pẹlu atupa wọn ni yiyi soke ti o si n jo lọwọ wọn, wọn wọle lọ si ibi iyawo. Awọn alailọgbọn ti jẹ́ alabikita nipa nini aniṣẹku ororo, atupa wọn si ti kú. Ni ibi pupọ ninu Iwe Mimọ́ ni ororo jẹ́ apẹẹrẹ Ẹmi Ọlọrun. Awọn alaigbọn kò rin ninu imọlẹ tó lati ni ororo aniṣẹku, wọn si ti jẹ ki eyi ti wọn ni jò danu. Awọn ọlọgbọn ti lo gbogbo anfaani ti wọn ni lati kún fun Ẹmi. Lẹyin ti a ti fi Ẹmi Mimọ baptisi wọn, Oun, ani Ẹmi Otitọ, ti dari wọn sinu otitọ gbogbo O si ti fi hàn fun wọn pe Oluwa wọn fẹrẹ dé.

Wọn mọ̀ pe awọn alaibikita ati alainaani ki yoo wà ni imurasilẹ; nipa ikiyesara ni adura wọn mu ki Ẹmi ni maa bá wọn gbé, wọn si ti wà ni imurasilẹ nigba ti ipe dún. Ṣugbọn pẹlu awọn alaigbọn, kò ri bẹẹ rara. Nipa aibikita ati ainaani, atupa wọn ti kú, wọn si wà ni aimurasilẹ nigba ti igbe ta pé, “Wo o, ọkọ, iyawo mbọ̀; ẹ jade lọ ipade rẹ̀.” Bakan naa ni yoo rí nigba ti Ọkọ Iyawo ba de lati mu iyawo Rẹ̀. Awọn ti wọn ba mura tán yoo wọle lọ si ibi Ase Igbeyawo ti Ọdọ-agutan, awọn ti o ba si ṣẹku ni ode ni yoo la ipọnju nlá ni kọja ti yoo de ba ayé yii.

A ti fẹ Iyawo fun Jesu Kristi ná, Ọkọ Iyawo ọkàn rẹ̀. “Nitoripe awa li ẹ̀ya-ara rẹ̀, ati ti ẹran-ara rẹ̀, ati ti egungun rẹ̀” (Efesu 5:30). Ipinnu Kristi ni pe ki Oun le ni “ijọ ti o li ogo li aini abawọn, tabi alẽbu kan, tabi irú nkan bawọnni; ṣugbọn ki o le jẹ mimọ́ ati alaini àbuku.” (Efesu 5:27). Oun maa n fun ni ni oore-ọfẹ lati pese iru Iyawo bẹẹ silẹ ati lati mu un wà ni ipo bẹẹ ninu ayé isisiyii. A ṣẹgun nipa Ẹjẹ Ọdọ-agutan naa ati nipa ọrọ ẹri wa.

Olukuluku ọkàn ni o di ajigbese lati rin ninu imọlẹ ti o ti tan si ipa ọna rẹ̀. “Ṣugbọn bi awa ba nrin ninu imọlẹ, bi on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ni idapọ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo” (1 Johannu 1:7). “Eyi si ni iṣẹgun ti o ṣẹgun aiye, ani igbagbọ́ wa” (1 Johannu 5:4). Kò ṣe e ṣe lati ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun tabi ninu ileri Rẹ̀ ayafi bi a ba n rin ninu Imọlẹ Ọrọ naa. Bi ẹnikẹni ba kọ eyikeyi ninu imọlẹ ti o ba wá sọdọ rẹ̀, imọlẹ naa ti ó wà ninu rẹ̀ yoo di okunkun.

Ijọ Akọbi jẹ́ agbajọ eniyan kọọkan, o si le jẹ mimọ́ ati alaini abawọn bi a ti n wẹ olukuluku ẹya-ara rẹ̀ ti a si sọ ọ di mimọ́. Bi awọn ọmọ Ijọ yii bá gbagbe ẹ̀jẹ́ ati ifararubọ wọn si Jesu, a o dán wọn wò lati

tẹle "ẹlomiran" (ọlọrun ajeji) wọn o si gbagbe pé pataki ipinnu wọn ni lati ṣe ohun ti o wu Oluwa ati lati mura silẹ fun ọjọ́ ti Oun yoo padabọ wá mú awọn ti Rẹ̀.

### Awọn Ọkọ ati Awọn Aya

A fi ẹkọ kọ́ awọn ọkọ ati aya nipa ojuṣe wọn si ara wọn nipasẹ ẹkọ yii lori ifẹ ati isopọ Kristi si Ijọ Rẹ̀ yii. Ọpọlọpọ wahala, ibanujẹ, ati ikọsilẹ ni a o fẹku bi ọkọ ati aya bá jẹ́ ọmọ Ijọ ti Kristi jẹ́ Ori fún. Nigba ti ọkọ ba fẹran aya gẹgẹ bi Kristi ti fẹran Ijọ, oun funra rẹ̀ ki yoo jẹ́ ẹni ti n dá ijọgbọn silẹ ninu ile naa. Nigba ti iyawo bá si tẹriba fun ọkọ gẹgẹ bi Ijọ ti n tẹriba fun Kristi, ipa ti rẹ̀ ninu isopọ wọn yoo maa mú alaafia ati ifẹ tẹ̀ siwaju. Bi tọkọ taya bá gbọran si Ọrọ Ọlọrun, ti ihuwasi wọn si ara wọn ba si jẹ bi o ti yẹ, wọn yoo wà ni àye ti Ọlọrun ti ṣe ilana silẹ fun wọn nipa nini irẹpọ ayọ ninu ẹmi. Awọn ọmọ wọn yoo dagba wọn yoo si pè wọn ni alabukun fun. Ni igba pupọ ni a ti maa n gbọ́ ẹri awọn ẹni irapada ti wọn maa n kan saara si awọn baba tabi iya wọn ti wọn jẹ́ Onigbagbọ́, pe igbesi-aye wọn jẹ́ apẹẹrẹ rere ti o mu ki awọn ọmọ wọn paapaa fẹ lati tẹle ipasẹ wọn ni sisin Oluwa.

### Rira Igba Pada

Awọn Onigbagbọ́ ni iṣẹ nla lati ṣe nipa lilo akoko wọn. Paulu ṣi wa leti lati ra igba pada, nitori pe buburu ni awọn ọjọ. A ni lati lo akoko wa ni ọna ti o dara jù lọ ni jijere ọkàn fun Ijọba Ọlọrun. Ọpọlọpọ nnkan ti kò ṣe pataki ni o maa n wá siwaju eniyan lati ṣe, ṣugbọn Iyawo Kristi a maa ranti pe ojuṣe oun ekinni ni lati gbọran si ohùn Oluwa ki oun si jade lọ lati maa fun irugbin. O gbọdọ ṣe eyi bi o tilẹ jẹ pe idanwo ati idojukọ wà fun un.

Iyawo Kristi jẹ́ Iyawo ti o ni ibanujẹ lọjọ oni. Nisisiyii o n ru agbelebu rẹ̀. O jẹ́ mimọ́ ati alaini abawọn, a wẹ̀ ẹ́ ninu Ẹjẹ, a yọ́ ọ a si dan an wò bi wura, o n fẹ lati jẹ ọ̀kan ninu awọn ẹni itẹmọlẹ ayé, ati lati fara da ẹ̀gan nitori Orukọ Rẹ̀. Jesu jẹ́ Ẹni ikaanu ti O si mọ ibanujẹ, Oun si n fẹ pe ki Iyawo ti yoo bá Oun jọba jẹ́ ẹni ti o ti bá oun jiya. Akoko ti a wà yii sun mọ ipadabọ Ọmọ Ọlọrun girigiri. Lai pẹ anfaani ti a ni lati jere ọkàn fun Jesu yoo kọja. Lọjọ naa awọn meloo ni yoo kigbe, "Ikore ti kọja, ẹ̀run ti pari, a kò si gba wa la"! (Jeremiah 8:20)

Bi ayé ti n buru si i bakan naa ni Onigbagbọ gbọdọ maa tàn sii. Bi ayé ti n buru si i bẹẹ gẹgẹ ni ó n fẹ ni Ihinrere imọlẹ tó. Ni akoko ti Noa, gbogbo ero ọkàn awọn eniyan kiki ibi ni lojoojumọ. Ṣugbọn Noa dá aye lẹbi nitori pe laaarin iwa buburu gbogbo, o gba Ọlọrun gbọ́. Nigba ti akoko kikun omi si dé, Noa ati awọn ara ile rẹ̀ fó loju omi, gẹgẹ bi Iyawo Kristi yoo ti goke lọ kuro ninu ogbologbo ayé yii ni igba Ipalarada. Oun yoo si wà ni ibi Ase-alẹ Igbeyawo Ọdọ-agutan nigba ti ẹkunrẹrẹ ibinu Ọlọrun yoo tú jade sinu ayé ni akoko Ipọnju Nla. Ọna ti o peye ju lọ lati ra igba pada tabi lati lo akoko wa ni lati mura silẹ fun ipadabọ Oluwa ki a si tun jẹ́ iranwọ fun awọn ẹlomiran lati mura silẹ.

## AWỌN IBEERE

1. Ta ni i ṣe Ori Ijọ?
2. Iru Ijọ wo ni Kristi n fẹ́ fun ara Rẹ̀?
3. Iru ifẹ wo ni ọkọ ni lati ni si iyawo rẹ̀?
4. Bawo ni iwa iyawo si ọkọ rẹ̀ ṣe ni lati ri?
5. Idi wo ni a fun wa ninu ẹkọ yii ti o n rọ̀ wa lati ra igba pada?
6. Bawo ni iwa wa si iṣẹ okunkun ṣe ni lati ri?
7. Ki ni awọn nnkan ti a kà silẹ ninu ẹkọ yii pe wọn n ti ilẹkun Ijọba Kristi mọ́ eniyan ti wọn si n fa ibinu Ọlọrun wá sori awọn ọmọ alaigbọran?
8. Irú ipo wo ni Ijọ ni lati wà ki a to le mu un wá sọdọ Kristi?
9. Ki ni awọn nnkan ti o le mú Ijọ wà ni imurasilẹ fun ipalarada?